# ÌGBÌMỌ̀ FÚN ÀJỌSỌ̀RỌ̀PỌ̀ LÁÀÁRÍN ÀWỌN ẸLẸ́SÌN

# TÍ PÁPÀ MÍMỌ́ GBÉ KALẸ̀

## ÌKÍ-NI KÚ ỌDÚN ÌPARÍ RÁMÁDÀN
## ‘Id al-Fitr’ 1433 H. / 2012 A.D.

### *Ẹ̀kọ́ lórí ìṣòdodo àti àlàáfíà fún àwọn ọ̀dọ́ Krístíánì àti Mùsùlùmí*

Láti Ìlú Fátíkánì

A kí ẹ̀yin ọ̀rẹ́ wa Mùsùlùmí,

1. Ayẹyẹ ọdún Id al-Fitr tí a fi parí oṣù Rámádán yìí fún àwa ọmọ Ìgbìmọ̀ Àjọsọ̀rọ̀pọ̀ láàárín Àwọn Ẹlẹ́sìn láyọ̀ láti fi tọkàn-tọkàn kí yín pé ẹ kú ọdún.

A bá yín yọ̀ fún oríire ìgbà yìí tó fún yín lánfààní láti mú bí a ti ń ìtẹ́ríba fún Ọlọ́run jìnlẹ̀ sí i nípa gbìgbààwẹ̀ pẹ̀lú iṣẹ́ ìfọkànsìn mìíràn, àwọn iṣẹ́ tó jọ wá lójú tó sì jẹ tiwa bákan náà.

Nítorí náà, lọ́dún nìí, a ń lo àyè tó ṣí sílẹ̀ yìí láti jùmọ̀ jíròrò lórí ẹ̀kọ́ fún àwọn ọ̀dọ́ wa ní Krístíánì àti Mùsùlùmí lórí ìṣòdodo àti àlàáfíà tó parapọ̀ mọ́ òtítọ́ àti òmìnira.

2. Bí a bá fi iṣẹ́ ẹ̀kọ́ lé ọwọ́ gbogbo ará ìlú, gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yín náà ti mọ̀, ṣíwájú pátá ló tọ̀ sí àwọn òbí ọmọ, pẹ̀lú wọn ló tún kan àwọn ará ilé, àti ilé ẹ̀kọ́ láti àkọ́bẹ̀rẹ̀ dé unifásitì, láì gbàgbé àwọn olùkọ́ ìgbàgbọ́, fún ẹ̀kọ́ lórí ìwà ọmọlúàbí, ìbára ìlú gbé pọ̀, ọ̀nà ajé tàbí okòwò, àti bí a ti ń bára sọ̀rọ̀ lóríṣiríṣi ọ̀nà.

Bí iṣẹ́ náà ti lẹ́wà tó ló sì ní ìṣòrò tó: ìyẹn ní ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn ọmọdé àti àwọn ọ̀dọ́ kí wọn mọ rírì àwọn ohun ìlò ti Ẹlẹ́dàá fi jínkìí wọn, láti gbé ohun wọ̀nyí lárugẹ, kí wọn sì mọ bíbá ọmọnìkéjì lò lọ́nà ọmọlúàbí. Lórí ọ̀rọ̀ iṣẹ́ ẹ̀kọ́ kan náà ni Pápà Mímọ́ Benedíktì XVI sọ pàtó pé: “Nítorí náà ńkọ́, àwọn ẹlẹ́rí òdodo ṣe pàtàkí lónìí tó bẹ́ẹ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ, kì í ṣe ti àwọn olùkọ́ láìjẹ olùṣe … Ẹlẹ́rí òdodo ni ẹni tó kọ́kọ́ fi ìgbé ayé rẹ̀ kọ́-ní lẹ́kọ̀ọ́ tó gbé kalẹ̀.” (“Ọ̀rọ̀ fún Ọjọ́ Ayẹyẹ Àlàáfíà ní Àgbáyé” 2012). Pẹ̀lú-pẹ̀lù, kí a tún rántí pé ẹ̀kọ́ àwọn ọ̀dọ̀ dọ́wọ́ ara wọn fúnra wọn bákan náà, pẹ̀lú mímú òdodo àti àlàáfíà wá sínú ayé wọn.

3. Ìṣòdodo bẹ̀rẹ̀ lórí ìbọ̀wọ̀ fún ẹ̀dá ọmọ ènìyàn ní ẹni kọ̀ọ̀kan, lódindi àti ní pípé; a kò lè fi ẹni kẹ́ni ṣe àpínlé tàbí àfikún. Kí a rántí pé ìdẹ̀ra gbogboògbò gbáralé ìbara-ṣe-pọ̀ àti ìfẹ́ bí ọmọ ìyá! Fún àwọn onígbàgbọ́, ìṣòdodo tòótọ́ tí a fi ń ba ara wa lò pẹ̀lú ìfẹ́ sí Ọlọ́run mú gbogbo ìrẹ́pọ̀ jìnlẹ̀ gidi, ìrẹ́pọ̀ pẹ̀lú ara ẹni, pẹ̀lú àwọn ènìyàn mìíràn àti pẹ̀lú gbogbo ẹ̀dá. Àní sẹ́, wọ́n fihàn pé orísun ìṣòdodo ni pé gbogbo ènìyàn jẹ́ ẹ̀dá Ọlọ́run tí a pè láti jẹ́ ọ̀kan, àti ọmọ ìdílé kan náà. Ìríran ohun wọ̀nyí, ní kíka ìrònú ọkàn sí àti ìfàyèsílẹ̀ fún iṣẹ́ ẹ̀mí tó rékọjá, jẹ́ àtìlẹ́yìn fún ọkùnrin àti obìnrin onínú rere, ó sì ń pè wọ́n láti mú kí ẹ̀tọ́ àti iṣẹ́ ki ọwọ́ bọ ọwọ́.

4. Nínú ayé wàhálà wa òde òní, kíkọ́ àwọn ọ̀dọ́ nípa àlàáfíà ti di iṣẹ́ kíákíá lái jáfara. Kí a tó lè ṣiṣẹ́ náà bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ, a gbọ́dọ̀ mọ ohun tí ń jẹ́ àlàáfíà ní tòótọ́: kì í ṣe àìsí ogun nìkan, tàbí ìbára dọ́gbà ìfojú-kojú ipá, ṣùgbọ́n bí ó ti jẹ́ ẹ̀bùn Ọlọ́run bákan náà ni ó ti jẹ́ ohun tí ọmọ ènìyàn gbọ́dọ̀ gbìyànjú láti wá laidẹ́kun. Ó jẹ́ èso ìṣòdodo àti àbáyọrí ìfẹ́. Ó ṣe pàtàkì kí àwọn onígbàgbọ́ kọbiara sí iṣẹ́ ṣíṣe láàárín aládúgbò wọn: iṣẹ́ àánú, ìdàpọ̀ṣọ̀kan, ìbára-ṣe-pọ̀ àti ìfẹ́ni, tí wọ́n lè fi ko àwọn ìṣòro òde òní lójú: bí ìdàgbà sókè tó jọjú, àti ìgòkè àgbà ní gbogbo ọ̀nà, mímú ìjà kúró àti yíyanjú èdè-àìyédè, ní fí fẹnu ba díẹ̀ níbẹ̀.

5. Ní àkótán, a ń gba àwọn ọ̀dọ́ Mùsùlùmí àti Krístíánì tí wọ́n ka ìwé yìí níyànjú láti ní ẹ̀mí òtítọ́ àti òmìnira, láti jẹ́ òjíṣẹ́ tòótọ́ fún ìṣòdodo àti àlàáfíà, àti atọ́nà fún ìwà ọmọlúàbí tó ń bu ọlá fún ipò ọ̀wọ̀ àti ẹ̀tọ́ gbogbo ará ilú. A pè wọn láti ní sùúrù pẹ̀lú ìdúró ṣinṣin tó yẹ láti mú ohun wọ̀nyi ṣẹ. Kí wọn jìnnà sí ohun tí kò bójúmu, iṣẹ́ àgàbàgébè, tàbí ọ̀nà tí kò yẹ ọmọlúàbí. Àyàfí àwọn ènìyàn lọ́kùnrin lóbìnrin tí wọ́n fi tọkàn tara faramọ́ ohun wọ̀nyí ló lè mú ìdàgbà sókè ìṣòdodo àti àlàáfíà wáyé láàárín àwọn ènìyàn.

Kí Ọlọ́run mú ìbàlẹ̀ ọkàn àti ìrètí kún inú àwọn ọkàn, ìdílé àti agbo àwọn ènìyàn tí wọ́n ní ìfẹ́ láti jẹ́ ‘ohun ìlò àlàáfíà’!

A kí gbogbo yín kú ọdún, kú ìyèdún o.

Jean-Louis Cardinal Tauran
Alága

Bíṣọ́bù Àgbà Pier Luigi Celata
Akọ̀wé

Láti Fátíkánì, ọjọ́ kẹta oṣù Ògún 2012
From the Vatican, 3 August 2012

**PONTIFICAL COUNCIL**
**FOR INTERRELIGIOUS DIALOGUE**

00120 Vatican City

Telephone: 0039-06-6988 4321 / 06-6988 3648
Facsimile: 0039-06-6988 4494

**Email: dialogo@interrel.va**